Bibeli fun awon omode



# Omo Alade lati inu Odo

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: M. Maillot; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: M. Maillot; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Josefu, alakoso ile Ijipiti, ku! Gbogbo Ijipiti kedun pelu idile re. Olorun ti lo Josefueniti i se Heberu lati gba orilede naa kuro lowo



iyan. O je ologbon aladari ti awon eniyan nife pupo. Sugbon bayi, o ti ku.

O ti le nioodunrun odun bayi ti Josefu tik u.  Awon eniyan Josefu, awon Heberu, ti gbile ni Ijipiti.  Farao titun beru awon ara Heberu pe boya won le gbogun ti oun, o wa fi won se eru.



Farao ba awon Heberu lo lona to buru. O pon ni dandan fun won lati ko awon ilu nla. Sugbon bi o se n niwonlaara to, se niawon eru Heberu n po si i niye.



Lojo kan ikede buburu kan ti odo Fararo wa. "Gbogbo omokunrin ti a ba sese bi fun awon Heberu ni a gbodo so sinu odo Naili" Farao buburu yii pinnu lati din awon Heberu ku. Yoo pa awon omode pelu.



Idile kan ro o ninu ara won pe, “Kin ni a o wa se?” Won pinnu lati gbe omo won si odo Naili.  Won gbe e sinu agbon kan ti omi ko lee wo.



Agbon kekere ti a gbe omo naa si lefo lori awon koriko etido.  Kin ni yoo sele si omode jojolo yii?



Lati okere rere, egbon omo naa n wo bi omi odo se ngbe agbon naa laarin koriko odo.





Lojiji ni omobinrin Farao ati awon iranse re wa si odo lati we. Ko si bi a se le gbe agbon naa pamo. Boya oju won le fo o bi won se nkoja lo.

“E wo agbon kan! Wo o, o ninu koriko etido. Kin lo le wa ninu re?” Omobinrin Farao ni ki awon iranse re lo gbe apere naa wa. Nigba ti o si i, omo naa bere sii sokun. Omobinrin Farao wipe, “omo Heberu ni.”



"A, omo jojolo!  Ewo bi o ti rewa" O se e se ki omobinrin Farao ba omo yii soro ni ona ti opo awon agbalagba fi maa nba omode sere.  O tile le ba a soro ni Ede awon ara Ijipiti "ootchie-kootchie koo-ums."



Olorun gbodo ti fi ogbon to yato fun egbon omode yii. O sare to omobinrin Faraowa. “Se ki nlo wa okan ninu awon obinrin ara Heberu ti yio ba o to omo naa?” “Lo se bee” ni idahun ti omobinrin Farao fun un. Tani o lero pe omobinirin yii lo pe?



Iya mi!  Yara kankan wa!  O see se ki omo yii ma ni akoko lati salaye ohun to sele.  Awon mejeeji jo pada lo.



Ni odo naa, omobinrin Farao gbe omo naa. "Too fun mi. Maa san owo itoju re fun o. Pe oruko re ni Mose." Mose, ni ede Ijipitile tumo si omokunrin-omi.



A da Mose pada fun awon obi re ati idile re. Won ko o ki o le feran Olorun ati awon Heberu. Laipe yoo lo gbe ni aafin pelu omobinrin Farao. Olorun to gba okan re la, ti seto ojo ola to dara fun omo naa Mose.



Omo Alade lati inu Odo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Ekisodu ori Ikeji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.